## Numeri 11:1-35; Orin Dafidi 78:17-41
## ẸKỌ 99 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nigbati Ọmọ-enia ba de yio ha ri igbagbọ́ li aiye?" (Luku 18:8).**

### Ounjẹ Awọn Angẹli

Awọn Ọmọ Israẹli ti pagọ fun nnkan bi ọdun kan ni Oke Sinai, ni akoko ti Ọlọrun fun Mose ni Ofin, ti a si kọ́ Agọ Ajọ. Ni gbogbo akoko naa Ọlọrun ti rán manna si wọn lati jẹ. Ni oroowurọ -- ayafi ni ọjọ Isinmi – nigba ti a ba fa iri soke, ilẹ a funfun fún ounjẹ lati Ọrun wá. Ounjẹ ti o dara ni – Onisaamu pe e ni "onjẹ awọn angẹli" o si fun wọn ni gbogbo nnkan wọnni ti o wà ninu ounjẹ ti o n fun ni lagbara ati ilera. Sibẹ awọn Ọmọ Israẹli korira "onjẹ futẹfutẹ yi."

Ebi ni i ba pa awọn Ọmọ Israẹli kú sinu aginju, bi o ba ṣe pe Ọlọrun kò pese ounjẹ fun wọn. Nitori manna yii jẹ́ ohun ajeji, ko si ẹni ti o le wi pe o ṣeeṣi wà nibẹ ni. Awọn eniyan yoo kó o lọ, wọn yoo lọ̀ ọ́ di ounjẹ wọn yoo si yan an ninu iná, sibẹ eyi ti o ba ṣẹku sori ilẹ yoo yọ́ nigba ti oorun ba goke, bi o tilẹ jẹ pe ooru òòrùn kò to ti idana wọn. Lẹyin naa Ọlọrun sọ fun wọn pẹlu pe eyi ti yoo to fun ọjọ kan nikan ni ki wọn kó lẹẹkan. Bi o ba ṣẹku di ọjọ keji yoo yọ idin, yoo si maa rùn. Ṣugbọn ni ọjọ ti o ṣaaju ọjọ Isinmi, wọn yoo kó manna ti yoo to fun ọjọ meji, ki yoo si bajẹ. Lootọ ounjẹ lati Ọrun wá ni, ti Ọlọrun fi fun wọn lojoojumọ gẹgẹ bi wọn ti n fẹ ẹ.

Ọlọrun ti fun awọn eniyan wọnyii ni omi lati inu apata pẹlu nigba ti wọn ti i ba kú nitori oungbẹ, bi o ba ṣe pe wọn ko ri omi yii. Ni igba miiran, a sọ omi ti o korò di didùn ki wọn ba le mu un. Gbogbo wọnyii ni Ọlọrun ti ṣe fun awọn Ọmọ Israẹli lati ọjọ de ọjọ. Igbesi-ayé wọn ojoojumọ jẹ́ iyanu, o si n fi han pe wọn jẹ ọmọ Ọlọrun, Oun si n ṣe itọju wọn. Sibẹ wọn kùn si Ọlọrun!

### Itẹlọrun

Bi ẹni kan ba jẹ́ ẹni ti n ráhùn, yoo ri ohun kan ti yoo maa mu un kùn, bi o ti wu ki nnkan maa lọ deedee fun un to. Ọlọrun n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ ni itẹlọrun pẹlu ohun ti o ba fun wọn. O mọ aini wa, O si ti ṣeleri lati pese fun wa gẹgẹ bi Ọrọ Rẹ̀ ninu ogo (Filippi 4:19). "Iwa-bi-Ọlọrun pẹlu itẹlọrùn, ère nla ni . . . . . . . Bi a ba si li onjẹ ati aṣọ, ìwọnyi yio tẹ́ wa lọrùn" (1 Timoteu 6:6, 8). Eyi ni ohun ti Ọlọrun n beere lọwọ awọn ọmọ Rẹ̀. Nigba ti a ba ráhùn nipa awọn ohun ti o de ba wa ninu igbesi-aye wa, ki i ṣe ara wa, tabi awọn ọrẹ wa nikan ni a n kùn si, ṣugbọn a n kùn si Ọlọrun pẹlu. Bi a ko ba tilẹ sọ ọrọ kan, Ọlọrun mọ gbogbo ero wa. O si mọ eredi ti Oun fi dù wa ni awọn ohun kan ti awa ro pe o yẹ ki a ní. Bi a ba kùn nitori eyi, ti a si n beere awọn nnkan wọnni lọwọ Oluwa, Oun ko ni le mu ifẹ Rẹ lori wa ṣẹ, nikẹyin a o si jiya idajọ Rẹ̀.

### Iná Ninu Agọ

A o ri ohun ti o ṣẹlẹ si awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn kùn laaarin gbogbo ohun ti wọn ní yii. Ọjọ mẹta pere ni wọn ṣi fi rìn lati Sinai, nibi ti wọn ti sinmi fun ọdun kan, ko si yẹ ki aarẹ ti i mu wọn pupọ. Sibẹ wọn rahun nitori ọna naa.

Awọn miiran wà, ti wọn ba awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni ilẹ Egipti, awọn ni a n pe ni adalu eniyan. Wọn ki i ṣe awọn ayanfẹ Ọlọrun gan an, ṣugbọn wọn ti wà pẹlu wọn fun ọdun kan gbako, agọ wọn si wà ni ẹba ibudo. O dabi ẹni pe laaarin wọn ni wahala akoko yii ti bẹrẹ. Nigba ti Ọlọrun gbọ́ kikun wọn, O rán iná ti o jó pupọ ninu wọn run.

Iná naa dẹru ba awọn Ọmọ Israẹli, wọn si sare lọ sọdọ Mose fun iranlọwọ. Mose gbadura, iná yii si kú. Ṣugbọn eyi ki i ṣe opin kikùn naa. Wọn dabi awọn ti i maa saba gbadura nigba ti iji lile ba n jà ti manamana si n kọ yẹri. Ẹru a maa ba wọn pe aara yoo san lu wọn, wọn yoo si ku, ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ti iji yii ba kọja tán, wọn yoo si tẹ̀ siwaju ninu ẹ̀ṣẹ wọn. Awọn ti ko ba ronupiwada nisisiyii ki yoo ni anfaani yii nigba ti Jesu ba de lati ṣe idajọ, ṣugbọn iná ni a o fi jẹ wọn niya gẹgẹ bi a ti ṣe fun awọn eniyan wọnyii – kiki pe eyi yoo jẹ́ iná ainipẹkun.

### Kikùn fun Ẹran

Lẹẹkan si i awọn adalu eniyan tun n fẹ nnkan ti Ọlọrun ko fi fun wọn, bẹẹ ni awọn Ọmọ Israẹli si tun gba ẹmi iráhùn naa wọn si n kigbe fun ẹran. Wọn ranti ẹja ti wọn n jẹ ni Egipti ati apalà ati alubọsa ati ewéko. O ṣẹṣẹ pe ọdun kan ti wọn bọ́ lọwọ awọn oluwa onrorò, ṣugbọn wọn ko ranti wakati pupọ ti wọn ti fi ṣiṣẹ pẹlu ilagbà; wọn ko si ranti tọsan toru ti wọn ti fi sọkun kikoro si Oluwa lati gbà wọn kuro ninu ilẹ buburu yii. Dipo ki wọn kun fun ọpẹ si Ọlọrun fun idasilẹ wọn kuro ni Egipti, ati fifun wọn ni ounjẹ lati jẹ, wọn kùn nitori ẹran.

Nigba ti a bẹrẹ si i kaanu fun ara wa, ti ẹnu si n ya wa pe awọn miiran n ni ohun aye yii jù wa lọ, a ni lati ka awọn ibukun wa. Lai pẹ a o ri pe a ni ohun pupọ lati dupẹ fun, to bẹẹ ti ẹmi kikùn yoo fò lọ patapata. Oluwa n fẹ ki a maa yọ̀ nigba gbogbo, ki a si maa dupẹ ninu ohun gbogbo.

**Irewẹsi Mose**

Ọpọlọpọ igba ni Ọlọrun n fẹ pa awọn Ọmọ Israẹli run nitori aigbọran wọn; Mose si ti gbadura kikankikan fun wọn, a si ti dá ẹmi wọn si. Ṣugbọn nikẹyin, Mose pẹlu rẹwesi nitori irahun wọn, o si beere lọwọ Ọlọrun eredi ti oun yoo fi ru ẹru aṣiwaju awọn alaimoore eniyan bayii. A ranti pe aadọjọ ọkẹ (3,000,000) eniyan ni wọn, Mose nikan ni o si n boju to iṣoro wọn. O daju pe awọn Ọmọ Israẹli ko jẹ iranwọ fun un nigba ti wọn n fi igba gbogbo kùn si Ọlọrun ti Mose fẹran ti o si fẹ gbọran sí lẹnu. Iṣẹ ti Ọlọrun fun Mose lati ṣe yii su u to bẹẹ ti o fẹ lati kú.

Bi o tilẹ jẹ pe ko tọna fun Mose lati sọrọ lodi si ipè giga ti Ọlọrun fi fun un, sibẹ Oluwa ko da a lẹbi. Inu Ọlọrun tikara Rẹ paapaa bajẹ ni ọpọlọpọ igba nitori aigbọran awọn Ọmọ Israẹli, O si fẹ ké wọn kuro.

**Awọn Aadọrin Agbaagba**

Ọlọrun sọ fun Mose lati yan aadọrin ninu awọn agbaagba Israẹli lati ràn án lọwọ. Ẹmi Ọlọrun yoo ba le wọn, wọn yoo si ni ọgbọn ati oye lati ṣe ohun ti Mose n ṣe, ni iwọnba. Awọn Ju gbagbọ pe eyi ni ibẹrẹ igbimọ wọn ti a n pè ni Sanhedrin, eyi si ni igbimọ ti o n ṣe akoso wọn ni igba aye Kristi.

Nigba ti awọn agbaagba wọnyii pejọ sinu Agọ lati ṣe ifẹ Ọlọrun, Ẹmi Rẹ̀ ba le wọn, wọn waasu, wọn si yin Oluwa logo. Bawo ni oju rere Ọlọrun si awọn ti o mu inu Rẹ̀ dun ti san ju ibinu Rẹ si awọn ti o kùn lọ! Mose kò sọ ọ̀kan ninu agbara rẹ̀ nù rara nigba ti a fun awọn agbaagba wọnyii ni ẹmi kan naa ti o wà lara rẹ̀. Oore-ọfẹ Ọlọrun pọ̀ lọpọlọpọ, ko si le ṣe alaito fun ẹni kan nitori a fi fun awọn miiran pẹlu. Dipo eyi, bi awọn eniyan ba ti le gbadura fun Ẹmi Ọlọrun lati wá sinu ọkan wọn tó ni yoo ti tan kalẹ sọdọ awọn ẹlomiran to, gbogbo eniyan ni yoo si dagba ninu oore-ọfẹ.

Meji ninu awọn ti Mose yàn gẹgẹ bi awọn alagba ko goke lọ sinu Agọ Ajọ, ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun ba le wọn nibi ti wọn wà ninu ibudo, wọn si sọtẹlẹ pẹlu. Ẹru ba Joṣua pe Mose ko ni fẹ eyi, yoo si dabi ẹni pe ifororo-yan Ọlọrun ti n wọpọ jù. Ṣugbọn Mose ko jowu ẹnikẹni. O wi pe oun fẹ ki Ẹmi Ọlọrun ba le gbogbo eniyan, gbogbo wọn ni yoo si yẹ lati ṣiṣẹ fun Oluwa. Awọn alufaa Ọlọrun ki i jowu nigba ti Ọlọrun ba n bukun awọn ẹlomiran ti O si n tú Ẹmi Rẹ̀ jade sara wọn. Wọn n fẹ ki gbogbo eniyan fi ara wọn rubọ de àye ibi ti Ọlọrun yoo ṣe gbogbo wọn ni oṣiṣẹ ninu oko ikore Rẹ̀.

**A Rán Ẹran**

Nigba ti Ọlọrun n fun Mose ni aṣẹ lati yan aadọrin agbaagba ti yoo ran an lọwọ, O ṣeleri lati rán ẹran sinu ibudo pẹlu. Ọlọrun ṣaanu fun Mose ninu aini rẹ̀, O si rán iranlọwọ. O fun awọn Ọmọ Israẹli ti wọn n kùn ni ifẹ ọkàn wọn, ṣugbọn idajọ tẹle e. O ṣeleri lati rán ẹran si wọn ti wọn yoo jẹ, eyi ti yoo to wọn fun oṣu kan – to bẹẹ ti yoo di irira si wọn, ti yoo si maa yọ jade ninu ihò imú wọn.

O dabi ohun ajeji pe o ya Mose lẹnu ibi ti ẹran ti o pọ to bẹẹ yoo ti wa. Bi Ọlọrun ba wi pe Oun yoo rán ẹran, dajudaju, iṣẹ iyanu pupọ ni o ti ṣẹlẹ kọja ti i ba mu un mọ pe Ọlọrun le ṣe ohunkohun. Ṣugbọn awọn akọni ninu igbagbọ paapaa le ṣiyemeji bi wọn ba duro lati ronu bi Ọlọrun yoo ti pese. Ohun gbogbo ni ṣiṣe fun Ọlọrun, O si n fẹ ki a gbẹkẹ le Oun bi o tilẹ jẹ pe awọn nnkan ṣoro ti o si dabi ẹni pe ko ni ṣe e ṣe.

Lai pẹ afẹfẹ bẹrẹ si fẹ, àparò si bà yí ibudo ká. Awọn eniyan kó awọn ẹyẹ wọnyii jọ fun ọsan meji ati oru kan, wọn si sá wọn si oòrùn lati gbẹ ki wọn ba le ni ẹran fun igba pipẹ. Ṣugbọn idajọ Ọlọrun wà ninu awọn aparo wọnni. Awọn Ọmọ Israẹli oniwọra, ti wọn si n kùn wọnyii ni a fi ajakalẹ arun ti Ọlọrun rán saarin wọn pa. A si sin wọn nibẹ. Wọn ko ri Ilẹ Ileri nì nitori wọn kùn si Ọlọrun.

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni o ti pẹ to ti awọn Ọmọ Israẹli ti fi Egipti silẹ?
2. Ki ni ṣe ti iná bẹ́ silẹ ni opin ibudo?
3. Awọn wo ni adalu eniyan?
4. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli tun kùn le lori lẹyin eyi?
5. Njẹ Ọlọrun fun wọn ni ifẹ ọkàn wọn?
6. Ki ni ṣẹlẹ lẹyin naa?
7. Ki ni Bibeli sọ nipa itẹlọrun?